Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 202-215 | jan./ jun.2025.

# Àfihàn obìnrin nínú àwọn àsàyàn orin àlọ onítàn yorùbá

# A representação das mulheres nas canções folclóricas iorubás

**Abídèmí BỌ́LÁRÌNWÁ, Ph.D** *
ORCID iD https://orcid.org/0009-0007-2718-3870

**ÀSAMỌ̀**
Ọ̀kan pàtakì lára ewì alohùn Yorùbá ni àlọ́ onítàn jẹ́. Àlọ́ wà fún ìdárayá, ìgbádùn àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́. Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ iṣẹ́ ìwádìí ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí àlọ́ onítàn Yorùbá ṣùgbọ́n kò fi bẹ́ẹ̀ sí ẹ̀yí tí ó sọ̀rọ̀ nípa obìnrin. Lọ́nà àti dí àlàfo yìí, a lo tíọ́rì ìfojú ìhun wò èyí tí ó sọ pe lítíréṣọ̀ lè ní ìtumọ̀ tí ó gbòòrò ju ẹyọ ọ̀rọ̀, gbólóhùn tàbí ohun tí ó wà ní ojú ìwé lọ èyí tí Ferdinand Sassure ṣe agbátẹ̀rù rẹ̀ ṣe àtẹ̀gùn láti ṣe àfihàn obìnrin nínú àwọn àsàyàn orin àlọ́ onítàn Yorùbá. Ó hàn gbangba pé ọ̀nà méjì gbòòrò ni a gbà fi obìnrin hàn nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá. Lọ́nà kíní a fi obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí aya rere, abiamọ tòótọ́, àti oníwà rere, bákan náà ni a tún fi obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí òjòwú, ọ̀dájú àti ìkà. Ìgúnlẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé lòdì sí ohun tí àwùjọ ń sọ nípa obìnrin kìí ṣe pátápátá ni ọ̀pọ̀lọ́ obìnrin kò nírù, bẹ́ẹ̀ ni kìí ṣe pé kò sí iṣẹ́ rere kankan lọ́wọ́ àwọn obìnrin. Fún ìdí èyí, ojú àìsègbè tí a fi wo obinrin nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá ni ó yẹ̀ kí àwùjọ ṣe àmúlò, kí wọ́n fi ahọ́n rere pe obìnrin ni ibi tí ó bá ti yẹ, kí ìtẹ̀síwájú àti ìdàgbàsókè lè wà láwùjọ

**KÓKÓ Ọ̀RỌ̀**
Obìnrin, Orin, Àlọ́ Onítàn, Ìfojú-Ìhun-Wo

**RESUMO**
Um dos aspectos mais importantes da poesia vocal Yorùbá é a história. A história serve para entretenimento, prazer e educação. Estudiosos realizaram pesquisas sobre a história Yorùbá, mas não se concentraram na história das mulheres. Para preencher essa lacuna, utilizamos a teoria da percepção visual, que afirma que a literatura pode ter um significado mais amplo do que as palavras, frases ou objetos na página que Ferdinand Sassure usou para descrever as mulheres nos poemas selecionados da história Yorùbá. É evidente que existem duas maneiras amplas pelas quais as mulheres são retratadas no folclore Yorubá. De um lado, as mulheres são retratadas como boas esposas, mulheres honestas e mulheres virtuosas, e de outro, as mulheres são retratadas como ciumentas, invejosas e cruéis. A conclusão deste estudo é que, ao contrário do que a sociedade diz sobre as mulheres, elas não são completamente impotentes, nem que elas não tenham boas ações. Por essa razão, a visão imparcial das mulheres no folclore iorubá é importante para que a sociedade adote, para dar às mulheres um nome positivo ao qual elas pertencem, para que o progresso e o desenvolvimento possam ocorrer na sociedade.

**PALAVRAS-CHAVE**
Mulher, Música, Folclore, Turismo

* Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Nigeria
E-mail: aobolarinwa@yahoo.com

**Ìfáàrà**

Àlọ́ jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí àwọn Yorùbá máa ń gbà láti kọ́ ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ èyí tí ó ń fi ọgbọ́n, ìmọ̀, òye, ìgbàgbọ́ àti ìṣesí àwọn Yorùbá hàn. Àlọ́ ni a lè pè ní ọmọ ìtàn, èyí tí a máa ń pa láti sọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀ ní ọjọ́ pípẹ́ séyìn láti lè fi eléyìí kọ́ ọmọdé bí a ṣe ń ronú jinlẹ̀ fún ìmọ̀ àtinúdá àti láti dárayá lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́ wọn. Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni àwọn Yorùbá máa ń sọ pé "Ọmọdé ló ni àlọ́, àgbà ló nìtàn". Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ló jẹ́ pé àgbà ló máa ń pá àlọ́ fún àwọn ọmọdé. Asúfèé yàgbàdo, fara jole, fara jolóko ni àlọ́ jẹ́ nínú ewì àtẹnudẹ́nu Yorùbá. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé àlọ́ máa ń yàtọ̀ sí àwọn ewì àtẹnudénu Yorùbá yòókù. Ní ìgbà mìíràn, ìbẹ̀rẹ̀ àlọ́ máa ń dàbí ìgbà tí a ń ke ewì, ìgbà mìíràn ó sì lè jẹ́ ọ̀rọ̀ wuuru. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni àwọn onímọ̀ ti o ti fún àlọ́ ní oríkì kan tàbí òmíràn. Ní èrò Ọ̀pádọ̀tun (1994:1) àlọ́ jẹ́ oríṣìí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tí a máa ń lò fún ìdárayá, ìgbádùn àti ìkónilẹ́kọ̀ọ́. Àlọ́ ìjàpá àti àlọ́ àpagbè ni àwọn onímọ̀ bíi Òjó (2005) àti Babalọlá (1978) pé àlọ́ tẹ́lẹ̀ ṣùgbọ́n ó dájú pé orúkọ yìí kò kógojá nítorí kì í ṣe ìjàpá nìkan ni ẹ̀dá ìtàn tí ìtàn àlọ́ máa ń dá lé lórí. Àwọn ẹ̀dá ìtàn mìíràn bí ẹyẹ, kòkòrò, iwin àti àwọn ẹ̀dá ìtàn mìíràn náá máa ń kópa nínú ìtàn àlọ́, fún ìdí èyí, ìtàn àlọ́ ni orúkọ tí ó ṣe ìtẹ́wọ́gbà yálà ó jẹ́ nípa ìjàpá tàbí àwọn ẹ̀dá ìtàn mìíràn tàbí èyí tí ó ni orin ègbè tàbí èyí tí kò ní.

Àbùdá kan pàtàkì tí àlọ́ ní ni pé àwọn ohun tó wà ní àrọ́wọ́tó tàbí àyíká ni ó máa ń jẹyọnínú àlọ́. A máa ń bá ènìyàn, ẹyẹ, ẹranko, iwin àti àkúdàáyá pàdé nínú ìtàn àlọ́, èyí nìkan kọ́, àwọn ohun abẹ̀mí àti aláìlẹ́mìí náà máa ń ní àjọṣepọ̀ nínú àlọ́. Nínú ìtàn àlọ́, a kìí lo orúkọ abáyému fún àwọn ẹ̀dá ìtàn nítorí pé èyí lè dá rúgúdù sílẹ̀ láàrin ẹni tí ó ń pa àlọ́ àti ẹni tí orukọ rẹ̀ bá papọ̀ pẹ̀lú ti ẹ̀dá ìtàn tí a bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà àìdára tí ó hù. Èyí nìkan kọ́, bí ẹni tí ó ń pa àlọ́ bá tún lo orúkọ ajẹmẹ́sìn fún ẹ̀dá ìtàn tí ó hu ìwà ìbàjẹ́ nínú àlọ́, àwọn ẹlẹ́sìn bẹ́ẹ̀ lè máa fi apá jánú pé ẹni tí ó ń pa àlọ́ náà ń tàbùkù ẹ̀sìn àwọn ni. Lọ́nà àti yàgò fún wàhálà tàbí dúkùú apàlọ́ kì í lo orúkọ abáyému fún àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀.

Inú ẹsẹ ifá ni àlọ́ ti jáde. A tilẹ̀ gbọ́ pé àlọ́ jẹ́ ọmọ Odùduwà nípasẹ̀ ifá, a ní láti mọ̀ pé ní ilẹ̀ Yorùbá babaláwo kì í pa àlọ́ nítorí wọn gbàgbọ́ pé ifá tí wọ́n dá ni ọjọ́ ọjọ́un ló padà wá di àlọ́ nípà báyìí àwọn òtítọ́ inú ifá ti sọnù, àyọkúrò àti àfikún sì ti pọ̀ rẹpẹtẹ àti pé oríṣìíríṣìí ọ̀rọ̀ àtinúdá ló ti wọ inú àlọ́. Àlọ́ pípa jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì láti kọ àwọn ọmọdé ní àṣà, ìwà ọmọlúàbí, àwọn ohun tó tọ́ láti ṣe àti àwọn ìwà tí àwùjọ korò ojú sí. Lára àwọn ìwà ti àlọ́ fi n kọni ní ìwà Iforítì, ìsoore, ìgboyà, ìsẹ̀ra-ẹni àti ìfẹ́. Ọ̀nà mẹ́rin gbòòrò ni a lè pín àlọ́ sí. Àwọn ìsọ̀rí náà ni: àlọ́ Àpamọ̀, Àlọ́ Àpagbè, Àrọ̀ àti Ìmọ́.

Àlọ́ àpamọ̀ jẹ́ amóríyá, ó máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé jáfáfá, èyí sì máa ń jẹ́ kí wọ́n tètè ronú jinlẹ̀ àti láti ṣe àkíyèsí àyíká wọn. Àlọ́ onítàn ni àlọ́ àpagbè jẹ́ oríṣìíríṣìí nǹkan ni àlọ́ yìí máa ń dálé. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé àlọ́ onítàn kì í ṣe òótọ́, o le dálé ènìyàn, ẹranko, iwin, ẹyẹ àtí igi. Àlọ́ onítàn lè jẹ́ èyí tí ó ni orin ègbè tàbí èyí tí kò ní. Gẹ́gẹ́ bí Àkàngbé (2016) ṣe sọ, "àlọ́ onítàn ni àwọn Yorùbá máa ń lò láti kọ́ àwọn ọmọ wọn ní ẹ̀kọ́, àwọn àgbà máa ń rí ẹ̀kọ́ kọ́ nínú àlọ́ onítàn pẹ̀lú. Àwọn àgbà tó ní ọ̀pọ̀ ìrírí ni ó máa ń pa àlọ́ fún àwọn ọmọdé. Ní ilẹ̀ Yorùbá alẹ́ ni wọ́n máa ń pa àlọ́ fún àwọn ọmọdé, ẹni tí ó bá pa àlọ́ ní ọ̀san tàbí òwúrọ̀ ni ilẹ̀ Yorùbá ni wọ́n mọ̀ sí olóòraye nítorí pé àwọn ẹ̀yà Yorùbá gbàgbọ́ pé àárọ̀ lọjọ́, àti pé iṣẹ́ ni a fi ń ṣe. Gbàgede tàbí àgbàlá ni àlọ́ pípa ti máa ń wáye. Orí ẹní tàbí àpótí kékeré ni àwọn ọmọdé máa ń jókòó sí láti gbọ́ àlọ́. Àwọn ọmọdé náà máa n pa àlọ́ láàrin ara wọn, bí àgbàlagbà kò bá sí ni itòsí. Ọ̀nà kan pàtàkì láti kọ́ni ni ẹ̀kọ́ ̀ìwà lóríṣìíríṣìí ni àlọ́ onítàn jẹ́. Àfojúsùn àlọ́ ni láti dánilẹ́kọ̀ọ́ láti ṣe ohun tí o tọ́ láwùjọ àti láti jìnnà sí àwọn ìwà tí àwùjọ kò fi àyè gbà lọ́nà àti mú kí àlàáfíà jọba, kí ìdàgbàsókè sì bá àwùjọ.

Onírúurú ìwúlò ni àlọ́ ni yálà ó jẹ́ àlọ́ àpamọ̀ tàbí àlọ́ onítàn. Àwọn ìwúlò wọ̀nyí ni a ó máa sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ báyìí. Àlọ́ onítàn máa ń dánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tàárà ni èyí tí o túmọ̀ sí pé ní òpin ìtàn àlọ́ ẹni tí ó bá ṣe rere yóò kẹ́san ìwà rere rẹ̀, ní ìgbà ti ẹni tí o bá ṣì hu ìwà búburú yóò kẹ́san búburú rẹ̀ bákan náà, fún ìdí èyí, àlọ́ onítàn máa ń kọ tọmọdé tàgbà ní ẹ̀kọ́ ìwà.

Ní ilẹ̀ Yorùbá, erémọdé ni ó máa ń padà di ọ̀rẹ́mọdé. Àjọsepọ̀ tí àwọn ọmọ máa ń ní lásìkò tí wọ́n bá ń gbọ́ àlọ́ máa ń mú kí ìfẹ́ àti ìrẹ́pọ̀ wa láàrin wọn, ọ̀pọ̀ àwọn ọmọ wọ̀nyí ni wọn sì máa ń di ọ̀rẹ́ tí wọn yóò sì ṣe ọ̀rẹ́ yìí di ọjọ́ alẹ́. Àlọ́ máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé ní ọgbọ́n àtinúdá torí ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni àwọn ọmọdé yìí máa ń tún àwọn àlọ́ tí wọ́n ti gbọ́ ni ẹnu àwọn àgbà sọ fún ara wọn ni ìgbà tí àwọn àgbà kò bá sí ní itòsí láti sọ àlọ́ fún wọn tàbí ní ìgbà tí ọwọ́ àwọn àgbà bá di, àwọn ọmọdé yìí pẹ̀lú ọgbọ́n àtinúdá ti wọn lè ṣe àfikún tàbí àyọkúrò sí àwọn àlọ́ tí wọ́n ti gbọ́ tẹ́lẹ̀. Àlọ́ máa ń tan ìmọ́lẹ̀ sí ohun tí ó sókùnkùn sí àwọn ọmọdé ni. Orísìírísìí àlọ́ onítàn ló máa ń tọ́ka sí ìdí abájọ èyí tí o sì máa ń mú kí àwọn ọmọdé kọ́ ẹ̀kọ́ kan tàbí òmíràn. Fún àpẹẹrẹ àlọ́ onítàn tí ó sọ̀rọ̀ nípa ìdí tí orí Ìjàpá fi pá kọ́ àwọn ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ pé ìwà ojúkòkòrò àti olè kò dára rárá. Bí àwọn ọmọdé bá tilẹ̀ fẹ́ hu ìwà búburú kan, bí wọ́n bá ti rántí àtubọ̀tán ìwà ojúkòkòrò

Ìjàpá èyí tí ó sọ ọ́ di olórí pípá, wọn yóò tún èrò wọn pa. Àlọ́ máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé mọ̀ nípa orísìírísìí ohun tí ó wà ní àyíká wọn, èyí tí ó jẹ́ pé wọ́n lè ṣe aláìmọ́ wọn bí kò ṣe pé wọn gbọ́ ọ nínú àlọ́. Ọ̀pọ̀ àwọn ọmọdé lóde òní tí kò ní àǹfààní sí àwọn àlọ́ wọ̀nyí ni kò ní ìmọ̀ tó nípa àwọn ohun tí ó wà ní àyíká wọn. Ìgboyà tún wà lára àǹfààní ti àlọ́ máa ń fún àwọn ọmọdé, ọ̀pọ̀ ọmọ ni kì í fẹ́ láti sọ̀rọ̀ láàrin ẹgbẹ́ ṣùgbọ́n ní ìbẹ̀rẹ̀ àwọn àlọ́ onítàn apàlọ́ lè bèèrè àwọn àlọ́ àpamọ̀ bíi mélòó kan fún ìdárayá àti ìmúrasílẹ̀ fún àlọ́ onítàn ó sì lè pe ẹni tí ó wù ú, èyí máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé wà ní ìmúrasílẹ̀ pẹ̀lú ìgboyà torí wọn kò mọ ẹni tí apàlọ́ lè pè.

Àlọ́ máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé ní àròjinlẹ̀ pàápàá àlọ́ àpamọ̀, ọ̀pọ̀ àwọn àlọ́ àpamọ̀ ló jẹ́ pe ọmọdé tí kó bá le ronú jinlẹ̀ dáadáa kò ní lè dáhùn irú àlọ́ àpamọ̀ bẹ́ẹ̀. Ọ̀pọ̀ ìgbà ló sì jẹ́ pé àwọn ọmọdé wọ̀nyí máa ń fi ara wọn ṣe yẹ̀yẹ́ bí wọ́n bá kùnà láti dáhùn àlọ́, lọ́nà àti dènà èyí àwọn ọmọdé máa ń ronú jinlẹ̀, wọ́n sì máa ń wà ní ìmúrasílẹ̀. Ìdárayá ní àlọ́ wà fún lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́, inú àwọn ọmọdé máa ń dùn, ara wọn sì máa ń yá gágá lásìkò tí wọ́n bá ń gbọ́ àlọ́, gbogbo ọmọdé ló máa ń wọ̀nà fún àsìkò àti gbọ́ àlọ́ yìí, èyí sì máa ń mú ara wọn yá gágá.

Àlọ́, pàápàá àlọ́ àpamọ̀ máa ń jẹ́ kí ọpọlọ àwọn ọmọdé jí pépé, torí àlọ́ tí wọ́n ń gbọ́ láti ìgbà dé ìgbà máa ń fi ìmọ̀ kún ìmọ̀ wọn ni, Ó sì máa ń mú ìrònú wọn jinlẹ̀. A tún máa ń fi àlọ́ parí ìjà tàbí aàwọ̀ ni ilẹ̀ Yorùbá. Ní ìgbà tí a bá pa àlọ́ yìí tàn ẹni ti ọ̀rọ̀ kan yóò ti rí ẹ̀kọ́ kan tàbí méjì kọ́ pé ìjà kò dára àti pé a rẹ́ ma jà kan kò sí. Àwọn ọmọdé máa ń kọ́ orin ní ìgbà tí wọ́n bá ń gbe orin àlọ́. Àwọn mìíràn nínú àwọn ọmọdé yìí lè tí ipasẹ̀ orin tí wọn kọ́ nínú àlọ́ onítàn yìí di ẹni tí ó ń kọ orin, tí yóò sì di olókìkì, ìwúlò tí ko ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn ni àlọ́ ní ní ilẹ̀ Yorùbá.

**Àgbéyẹ̀wò Iṣẹ́ Ìṣaájú Àlọ́**

Àlọ́ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn ewì alohùn Yorùbá tí a máa ń gbékalẹ̀ pẹ̀lú ìwéhùn tí a fi ń sọ̀rọ̀ ojoojúmọ́, òdú tí kìí ṣe àìmọ̀ olóko ni àlọ́ jẹ́ nínú àwọn ewì alohùn Yorùbá torí àlọ́ wà fún ìdárayá, ìgbádùn àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́. Gẹ́gẹ́ bí Ọ̀pádọ̀tun (1994) ṣe sọ, ọ̀rọ̀ aṣọdorúkọ ni “àlọ́”. Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ “a” pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe “lọ́” ni a papọ̀ tí ó di ọ̀rọ̀ orúkọ “àlọ́”. Ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe “lọ́” ni kí a di nǹkan tàbí wé nǹkan, tàbí lọ́ nǹkan mọ́ nǹkan mìíràn. Nínú àṣà ìsọ̀tàn Yorùbá, kò sí ohun tí a kò lè fi ti ipasẹ̀ ìfúnlórúkọ àti ìgbétànkalẹ̀ lọ́ mọ́ ara wọn. A lè lọ́ ènìyàn mọ́ ènìyàn, ẹranko mọ́ ẹranko, ènìyàn mọ́ ẹranko àti ohun ẹlẹ́mìí mọ́ èyí tí kò lẹ́mìí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí àlọ́.

Bascom (1949) ṣe àyẹ̀wò tó gbòòrò lórí onírúurú àlọ́ Yorùbá, nígbà tí Babalọlá (1974) pín àlọ́ àpamọ̀ Yorùbá sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́. Yai (1977) àti Ọlámbitán (1982) Ṣe àgbéyẹ̀wò àlọ́ àpamọ̀ Yorùbá àti ọ̀nà tí a ń gbà wá ìdáhùn sí i. Àjàyí (1990) ṣe atótónu lórí bí àlọ́ àpamọ̀ ṣe wúlò fún ìdàgbàsókè ọmọ Yorùbá tó. Ó kín ọ̀rọ̀ Bauchat (1957) lẹ́yìn pé àlọ́ àpamọ̀ jẹ́ àpapọ̀ ìtàn ìdánilárayá àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ dé ààyè ibi kan. Àjàyí (2015) ṣe ọ̀rinkínniwín àlàyé lórí àlọ́-àpamọ̀ pé kìí ṣe iṣẹ́ ẹnìkan. Bí ẹnìkan ti ń gbé ìbéèrè kan kalẹ̀ ni àwọn yòókù yóò má ronu ohun tí ó jẹ́ ìdáhùn sí ìbéèrè náà. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀, amóríyá àti aṣíniníyè ni àlọ́-àpamọ̀ àti pé ohun ni ó máa ń ṣíwájú àlọ́ onítàn.

**Obìnrin láwùjọ Yorùbá**

Atáyése àti kòṣeémánìí ni àwọn obìnrin, èyí ni ó ṣe jẹ́ pé kò sí lájọ, àjọ kò kún ni wọ́n. Àwọn gan an ni iyọ̀ ayé. Onírúurú ọgbọ́n àti ète ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ó wà lọ́wọ́ àwọn obìnrin èyí tí ó túmọ̀ sí pé kò sí bí ènìyàn ṣe lè gbọ́n nínú lẹ́yìn tó, tí obìnrin kò lè mú un. Gẹ́gẹ́ bí Babátúndé (1994) se sọ, oríṣìíríṣìí obìnrin ni ó wà, ọ̀kanòjọ̀kan èrò ní àwọn Yorùbá sì ní sí obìnrin. Àwọn Yorùbá ka obìnrin sí ẹ̀dá tí kò ní agbára, tí ó sì tún jẹ́ ohun ẹlẹgẹ́ tí Olódùmarè dá, ní gbogbo ọ̀nà ni èrò àti ìse. Gẹ́gẹ́ bi Fasehun àti Òjó (2015) ṣe tọ́ka sí i, oríṣìíríṣìí òǹkọ̀wé ajẹmóbìnrin ni ó ti ṣiṣẹ́ púpọ̀ lórí ọ̀rọ̀ obìnrin pàápàá nípa ìtúsílẹ̀ abo lọ́wọ́ àwọn akọ, yíyọ obìnrin nínú ẹrẹ̀ tí àwùjọ fi wọ́n sí, rírí obìnrin gẹ́gẹ́ bí aláìlágbára àti gbígba àwọn obìnrin sílẹ̀ lọ́wọ́ ìjẹgàba àwọn ọkùnrin.

Àwọn òǹkọ̀wé ajẹmóbìnrin tún gbìyànjú láti ṣe àgbéyẹ̀wò ipò, ojúṣe àti ojú tí a fi wo obìnrin nínú lítíréṣọ̀ lóníranràn. Ògúndìpẹ̀-Leslie (1984), Smith (1985), Acholonu (1999), Adébáyọ̀ (1996), Kọ́láwọlé (1998), Fasehun (2009), Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2009), Akóredé (2011) àti Ilésanmí (2013). Ohun tí àwọn òǹkọ̀wé ìṣègbèfábo tẹpẹlẹ mọ́ ni ọ̀nà tí òpin yóò ṣe dé bá àwọn ohun tí ó dúró gẹ́gẹ́ bí adínàgbookù nípa ẹ̀kọ́, ìkópa nínú ètò ìṣèlú, ìfààyè gbà obìnrin láti ṣe iṣẹ́ tí ó bá wù wọ́n, ipò àṣẹ, àwọn àṣà ìkóbìnrin lẹ́rú ní àwùjọ Yorùbá àti àwọn òfin tí kò fàyè gba ìdàgbàsókè obìnrin. Ohun tí ó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí ni ọ̀nà tí a gba ṣe àfihàn obìnrin nínú àwọn orin àlọ́ onítàn Yorùbá.

**Tíọ́rì Ànúlò**

Tíọ́rì tí ó jẹ àtẹ̀gùn fún ṣíṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí ni tíọ́rì Ìfojú-ìhun-wò lítíréṣọ̀. Kí a tó ṣe ìtúpalẹ̀ a gbọdọ̀ ṣe àmúlò tíọ́rì kan. Adéyẹmí (2006) sọ pe láti inú ìmọ̀ sáyẹ́nsì ni tíọ́rì ti jẹ yọ, ó ní tíọ́rì ni abẹ́fẹ́lẹ́ ìmọ̀ tí a fi ń la ìfun àti ẹ̀dọ̀ iṣẹ́ ọnà kan, Adéyẹmí túnbọ̀ ṣàlàyé pé nígbà tí a bá ṣe àmúlò tíọ́rì láti fi la ìfun àti ẹ̀dọ̀ iṣẹ́ ọnà kàn, ọgbọ́n àgbékalẹ̀ ìmọ̀, ìmọ̀-ọ́nṣe àti ète òǹkọ̀wé yóò túnbọ̀ yé àwọn òǹkàwé iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ sí i. Adéyẹmí túnsọ pé tíọ́rì máa n mú ìtẹ̀síwájú wá fún iṣẹ́ lámèyítọ́ nítorí ó jẹ ohun èlò fún iṣẹ́ ìtúpalẹ̀.

**Tíọ́rì Ìfojú-Ìhun-Wò**

Tíọ́rì Ìfojú-ìhun-wò jẹ́ tíọ́rì tí ó ní ṣe pẹ̀lú ìgbàgbọ́ pé ohun kan kò le dá ìtumọ̀ ní àfi bí a bá fi ojú wo àwọn nǹkan mìíràn tí wọ́n jọ so mọ́ ara wọn. Ó jẹ́ kí á mọ pé ìtumọ̀ tí lítíréṣọ̀ le ní gbòòrò ju ẹyọ ọ̀rọ̀, gbólóhùn tàbí ohun tó wà lójú ìwé lọ, ó jẹ́ kí á mọ pé lámèyítọ́ le ṣàmúlò gbogbo ìmọ̀, àṣà, ẹ̀sin, ìmọ̀-èdè linguistiki, ọgbọ́n, òye àti ìrírí lọ́nà àti fún lítíréṣọ̀ ní ìtumọ̀ tó péye. Lára àwọn onímọ̀ linguistiki tó jẹ́ agbátẹrù ìlànà tíọ́rì Ìfojú-ìhun-wò ni Jonathan Culleer àti Ferdinard dé Saussure. Àwọn ló mú ìlànà ìmọ̀ linguistiki wọ tíọ́rì yìí fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀, gẹ́gẹ́ bí Jonathan Culleer ṣe sọ, "kò sí ìtumọ̀ tí a kò le fún lítíréṣọ̀ níwọ̀n ìgbà tí a bá ṣàlàyé dáadáa tàbí ṣàwárí irú ìtumọ̀ bẹ́ẹ̀:

> Structuralism gives support to whatever interpretation to whatever that is given to literature since it deals with both the tangible and the intangible, observable and the non-observable elements in the test, relating them to thecorrect and pertinent context (Culler 1973:59).

Tíọ́rì yìí mú kí ó ṣẹ́ṣe láti fún iṣẹ́-ọnà tàbí lítíréṣọ̀ ní ìtúpalẹ̀ ìjìnlẹ̀ àti ìtumọ̀ tó múná dóko, tíọ́rì yìí jẹ́ mọ́ pé lámèyítọ́ tún lè ṣe àmúlò ìlànà mìíràn gẹ́gẹ́ bí àfikún fún ìlànà ojú inú láti ṣe àtúpalẹ̀, bí àpẹẹrẹ ṣíṣe àmúlò ìlànà ìtàn òǹkàwé. Gẹ́gẹ́ bí tíọ́rì tí ó ní ṣe pẹ̀lú ìbáṣepọ̀ láàrin nǹkan méjì, ó jẹ́ ká mọ̀ pé àṣepọ̀ tó ní ìtumọ̀ wà láàrin lítíréṣọ̀/iṣẹ́-ọnà àti oníṣẹ́ ọnà (ẹni tó ṣẹ̀dá ọnà), tíọ́rì Ìfojú-ìhun-wò ṣàfihàn pé ìtumọ̀ lítíréṣọ̀ tayọ ẹyọ ọ̀rọ̀, gbólóhùn tàbí ohun tó wà lójú ìwé nìkan lọ.

**Àwọn Àlọ́ Onítàn Yorùbá Tí a Gbé Yẹ̀wò**

Ní abala yìí, àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá tí a gbé yẹ̀ wò ní a ó máa jíròrò nípa wọn, àwọn àlọ́ wọ̀nyí ni: Olúrómbí àti Olúwéré, Ẹyẹ àgbìgbò àti obìnrin méjì, Awọn ayaba méjì, Orogún Búburú, Ìjàpá àti Bùjé, Àwọn Orogún Méjì, Ọmódé kan àti Ìyá rẹ̀, Ọmọdékùnrin àti Orogún Ìyá rẹ̀ àti Ọmọbìnrin alaìgbọ́ràn.

**Olúrómbí Àti Olúwéré**

Ní ayé àtijọ́, obìnrin kan wà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Olúrómbí. Obìnrin yìí kò finú soyún, bẹ́ẹ̀ ni kò fẹ̀yìn gbọ́mọ pọn, èyí jású pé ó yàgàn. Ó wá ọmọ títí ṣùgbọ́n pàbó ló ń já sí. Dípò kí ó dúró de iṣẹ́ Olódùmarè, ó gba ọ̀dọ̀ Olúwéré lọ. Ó ṣe eléyìí nígbà tí ó rí àwọn tí wọ́n jọ wà nínú ipò báyìí tí wọ́n ń gbọ́mọ pọn. Olúrómbí gbéra, ó lọ sí ọ̀dọ̀ Olúwéré. Pẹ̀lú ìtara ni Olúrómbí fi jẹ́ ẹ̀jẹ́ pé bí Olúwéré bá fún òun lọ́mọ, òun yóò sì fún un ní ọmọ náà. Ẹ̀jẹ́ yìí jẹ́ ọ̀tun nítorí pé, ewúrẹ́ àti àgùntàn ni àwọn obìnrin ń padà wá fún Olúwéré gẹ́gẹ́ bí ẹ̀jẹ́. Lóòótọ́, Olúrómbí lóyún, ó sì bí ọmọbìnrin kan tí ó sọ orúkọ rẹ̀ ní Apọ́nbí-epo. Apọ́nbíepo ń dàgbà, ìyá rẹ̀ kò sì rántí ẹ̀jẹ́ tí ó bá Olúwéré dá mọ́, nígbà tí Olúwéré retí Olúrómbí kí ó wá mú ẹ̀jẹ́ rẹ̀ ṣẹ tí kò ríi ni òun gan-an bá gbéra ní ọjọ́ kan ó gba ilé Olúrómbí lọ. Bí ó ṣe dé'bẹ̀ tí ó f'ojú kan Apọ́nbíepo ni ó bá lé lọ́wọ́ mú tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí mú un lọ.Ọmọ yìí bẹ̀rẹ̀ sí sunkún títí Olúwéré fi padà wọ inú igi lọ pẹ̀lú Apọ́nbíepo.

Olúrómbí bẹ̀rẹ̀ sí bẹ Olúwéré pẹ̀lú omijé lójú, ṣùgbọ́n dípò kí Olúwéré dá ọmọ padà, ori ni ó bẹ̀rẹ̀ sí fi dáa lóhùn báyìí pé:

Lílé: Oníkálukú ń jẹ̀jẹ́ ewúrẹ́,

ewúrẹ́, ewúrẹ́
Oníkàlùkù ń jẹ̀jẹ̀ àgùntàn,
àgùntàn bọ̀lọ̀jọ̀
Olúrómbí ń jẹ̀jẹ́ ọmọ rẹ̀, ọmọ
rẹ̀ Apọ́bíepo
Olúrómbí o o

Ègbè: Janin-janin, Ìrókò janin-jain
Lílé: Olúrómbí o o
Ègbè: Janin-janin, Ìrókò janin-jain

Báyìí ni Olúrómbí ṣe pàdánù ọmọ rẹ̀. Ìtàn yìí kọ́ wa wí pé bí a bá jẹ́jẹ̀ẹ́ kí á rí wí pé ẹ̀jẹ́ tí a lè san ni a jẹ́, kí á má máa fi ìwàǹwara jẹ́ ẹ̀jẹ́. Ní ẹ̀ẹ̀kejì ó yẹ kí á má kó gbogbo àníyàn wà ti Olódùmarè, kí á má máa fi ìwàǹrara wà nǹkan torí Ọba Òkè t'óṣe fún Táyé kò gbàgbé Kẹ́hìndé, ẹ jẹ́ kí á máa sọ́ra.

Ẹyẹ Àgbìgbò Àti Obìnrin Méjì

Ní ayé àtijọ́, ọkùnrin kan wà tí ó ní ìyàwó méjì. Èyí èkíní ní owó lọ́wọ́ dáadáa ṣùgbọ́n èkejì jẹ́ akúṣẹ̀ẹ́ tí ó jẹ́ pé ewé ni ó máa ń sà kiri nínú igbó. Ní ọjọ́ kan, obìnrin yìí lọ sí inú igbó láti lọ sa

ewé bí ìṣe rẹ̀. Ó tẹ ọmọ rẹ̀ sílẹ̀ ní abẹ́ igi kan òun náà sì bẹ̀rẹ̀ sí sa ewé kiri. Bí ó ṣe ń ṣe èyí ni ẹyẹ àgbìgbò tí ó ti bà lé orí igi tí ó sì ń wo obìnrin ní ibi tí ó ti ń sa ewé, ní ó bá fò wá sí ìsàlẹ̀, ó sì gbé ọmọ obìnrin yìí padà sí orí igi.

Nígbà tí obìnrin yìí sa ewé tán ó padà sí ibi tí ó gbé ọmọ rẹ̀ sí, ìyàlẹ́nu ló jẹ́ nígbà tí ó dé ibi tí ó gbé ọmọ sí tí kò bá ọmọ rẹ̀ níbẹ̀. Ó bẹ̀rẹ̀ sí dàámú kiri láti rí ọmọ rẹ̀, níbi tí ó ti ń dàámú kiri ni ó ti gbé ojú sókè tí ó rí ọmọ rẹ̀ tí ẹyẹ àgbìgbò ti gbé gun orí igi. Obìnrin yìí bẹ̀rẹ̀ sí bẹ ẹyẹ àgbìgbò kí ó gbé ọmọ òun fún òun, bí ó ṣe ń bẹ̀ẹ́ ni ó bẹ̀rẹ̀ sí

sọkún tí ó sì ń kọrin báyìí pé:

Lílé: Àgbìgbò gb'ọ́mọ mi

Kòmí ìgbó
Ègbè: Ẹẹyẹ ìgbò
kòmí ìgbò
Ègbè: Ẹẹyẹ ìgbò
Lílé: Ọmọ aládé orí igi
Ègbè: Ẹẹyẹ ìgbò
Lílé: Ọmọ òtòsì ilẹ̀ ọrọ̀
Ègbè: Ẹẹyẹ ìgbò
Lílé: Gb'ọ́mọ mi kòmí ìgbò
Ègbè: Ẹẹyẹ ìgbò

Nígbà tí ó pẹ́ ẹyẹ àgbìgbò bi obìnrin yìí léèrè bóyá yóò gba owó dípò ọmọ rẹ̀ ṣùgbọ́n obìnrin yìí sọ fún ẹyẹ àgbìgbò pé kò sí ohun tí ó lè fún òun tí ó lè tẹ́ òun lọ́rùn bí ọmọ òun. Nígbà tí ẹyẹ ìgbò rí i pé kò sí ohun tí obìnrin yìí ń fẹ́ bí kò ṣe ọmọ rẹ̀, ní ó bá mú ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó àti ẹrù, ó gbée fún obìnrin yìí, ó sì tún gbé ọmọ rẹ̀ fún un.

Inú obìnrin yìí dùn, ó sì padà lọ sí ilé, nígbà tí ó dé ilé, ó dá gbogbo ohun tí ẹyẹ igbó fún un sí méjì, ó kó idá kan fún ìyáálé rẹ̀. Ohun tí obìnrin yìí ṣe kò dùn mọ́ ìyáálé rẹ̀ nínú, ó kọ àwọn nǹkan náà ó sì ń sọ wí pé òun náà yóò lọ gba tí òun náà lọ́dọ̀ ẹyẹ ìgbò, ṣe ẹ rí ọ̀kánjúà obìnrin! Obìnrin kejì yìí náà gbé ọmọ rẹ̀, ó di inú igbó, nígbà tí ó dé inú igbó, ó gbé ọmọ rẹ̀ sílẹ̀, òun náà sì bẹ̀rẹ̀ sí sa ewé. Ó retí kí ẹyẹ ìgbò wá gbé ọmọ òun ṣùgbọ́n ẹyẹ náà kò gbé ọmọ rẹ̀, ni ó bá bẹ̀rẹ̀ síbẹ ẹyẹ ìgbò kí ó gbé ọmọ òun náà kí òun lè di ọlọ́là bí ìyàwó òun.

Ẹyẹ yìí mọ̀ pé òjòwú ni obìnrin yìí, ó sì pinnu láti kọ́ọ lọ́gbọ́n. Ẹyẹ àgbìgbò fò wá sí ìsàlẹ̀, ó sì gbé ọmọ òjòwúbìnrin yìí. Inú obìnrin yìí dùn pé ẹyẹ àgbìgbò gbé ọmọ òun náà, ẹyẹ ìgbò bíi léèrè ohun tí ó ń fẹ́, obìnrin yìí dáa lóhùn pé òun fẹ́ kí ẹyẹ ìgbò sọ òun náà di ọlọ́rọ̀ bí ìyàwó òun. Ẹyẹ ìgbò mọ̀ pé òjowú ni obìnrin yìí, ni ó bá fa itan ọmọ rẹ̀ kan já, ó sọ ọ́ sí obìnrin yìí. Obìnrin yìí bẹ̀rẹ̀ síi bẹ ẹyẹ ìgbò pé owó ni òun fẹ́, ẹyẹ àgbìgbò sì tún ya itan kejì ó tún sọ ọ́ sí obìnrin yìí. Nígbà tí obìnrin yìí rí ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ó bẹ̀rẹ̀ sí sun ẹkún, ó ń gbé ara dá ilẹ̀. Ní àsìkò yìí ni ẹyẹ ìgbò sọ ìyókù ọmọ rẹ̀ sílẹ̀ tí ó sì fò lọ. Obìnrin yìí sọkún títí ṣùgbọ́n kò sì àtúnṣe. Báyìí ni obìnrin yìí pàdánù ọmọ rẹ̀ torí owú jíjẹ tí kò sí tún ní owó tí ó fẹ́ ní. Ìtàn yìí kọ́ wa wí pé kí á máa ni ìtẹ́lọ́rùn, kí á má sì ṣe jowú ẹnìkejì wa.

**Àwọn Ayaba Méjì**

Ní ayé àtijọ, Ọba kan wà ní ìlú kan, Ọba yìí ní ìyàwó méjì, ọ̀kan nínú àwọn ìyàwó ọba yìí jẹ́ àkàndá, èyí túmọ̀ sí pé ó ní àléébù lára. Kín ni àléébù ayaba yìí? Àléébù rẹ̀ ni pé kò ní apá kan. Ayaba yìí kò sì fẹ́ kí ẹnìkankan mọ̀ nípa àléébù yìí, gbogbo ìgbà ni ó máa ń fi àléébù yìí pamọ́, ṣùgbọ́n ayaba kejì mọ̀ nípa àléébù yìí, ó sì fẹ́ tú àsírí náà síta.

Ní ọjọ́ kan, ayaba kejì lọ bá ọba, ó sọ fún ọba kí ó jẹ́ kí àwọn ṣe ìdíje àgbàdo gígún ní gbangba ìta, èyí tí ọba yóò pe gbogbo ìlú jọ sí, tí ọba yóò sì fún ayaba tí ó bá gún àgbàdo dáadáa ni ẹ̀bùn. Ète tí ó wà nídìí ìmọ̀ràn yìí ni láti tú àsírí ayaba tí kò lápá èyí tí kò sì hàn sí gbogbo ìlú. Lóòótọ́, ọba gbọ́ ọ̀rọ̀ yìí ó sì dá ọjọ́ tí wọn yóò wá ṣe ìdíje yìí ní gbangba, ṣe ọba kò mọ̀ pé ayaba òun kò ní ọwọ́ ni? Ọba mọ̀ ṣùgbọ́n òun náà wà ní ìdí rìkísí náà. Kí ó tó di ọjọ́ ìdíje, ayaba tí kò ní apá kan bẹ̀rẹ̀ sí gbàdúrà sí Olódùmarè, Ọba àánú, Ọba tí kì í dójú tini. Ní ọjọ́ ìdíje ìyànu ńlá ṣẹlẹ̀, ṣe ni apá ayaba tí kò tí sí níbẹ̀ ti bẹ̀rẹ̀ sí hù tí ó ń gùn díẹ̀ díẹ̀ tí ó fi gùn tó ọwọ́ kejì. Ayaba yìí fi ó gbé odó tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí gún àgbàdo. Nígbà tí ó gún àgbàdo kúnná tán ni wọ́n pe ayaba tí kò lọ́wọ́ láti wá gún àgbàdo. Ìyàlẹ́nu ló jẹ́ nígbà tí àgbàdo tí wọ́n dà sínú odó paradà di fàdákà, Lẹ́ẹ̀kan náà ni ayaba yìí yọ apá rẹ̀ nínú aṣọ tí ó na apá méjéèjì sókè tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí kọrin báyìí pé:

Lílé: Kò ní gúngbàdo o e e

Ègbè: Kò ní gúngbàdo

Lílé: Ayaba t'ó ń gún fàdákà
Ègbè: Kò ní gúngbàdo
Lílé: Ayaba t'ó ń gún fàdákà
Ègbè: Kò ní gúngbàdo

Bí ó ṣe ń kọrin yìí ni ó na apá rẹ̀ méjéèjì s'ókè tí gbogbo èniyàn hó yànmùn. Ẹnu ya ọba àti ayaba tí ó di ọ̀tẹ̀ yìí púpọ̀ bẹ́ẹ̀ ni ojú tì wọ́n. Báyìí ni ayaba tí kò tí ni apa kan wá di alápá méjì nínú ààfin. Ìdí àlọ́ yìí ni pé kò yẹ kí á máa ro èniyàn pin.

**Orogún Búburú**

Ní ayé àtijọ́, ọkùnrin kan wà tí ó ní ìyàwó méjì, èyí àkọ́kọ́ bí obìnrin, kò bí ọkùnrin, bẹ́ẹ̀ ni èyí ìyàwó bí ọmọkùnrin kan. Eléyìí fi hàn pé ọmọkùnrin yìí ni ni yóò jẹ́ àrólé. Inú ìyáálé kò dún sí eléyìí, ṣùgbọ́n ó f'ẹ̀jẹ̀ sínú tutọ́ funfun síta lásán ni. Nígbà tí ó pẹ́ baba kú, kò pẹ́ lẹ́hìn rẹ̀ tí ìyá ọmọkùnrin yìí náà kú. Inú orogún ìyá ọmọkùnrin yìí dùn, ó sì rò ní ọkàn rẹ̀ pé òun ṣetán láti fi ìyà jẹ ọmọkùnrin yìí. Obìnrin yìí ronú irú ìyà tí òun lè fi jẹ ọmọ yìí, kò pẹ́ ni ó bá ronú kan àwọn iṣẹ́ tí ó ṣòro fún èniyàn láti ṣe. Àwọn iṣẹ́ yìí ni ó ní òun yóò fún ọmọkùnrin yìí ṣe. Ó sì mú dá ọmọ náà lójú pé bí kò bá lè ṣe àwọn iṣẹ́ náà pípa ni òun yóò pàá. Àwọn iṣẹ́ tí yóò fún ọmọ yìí ni pé kí ó kọ ebè kí ebè náà ó kan ọ̀run, ó tún ní kí ọmọ yìí ó pa ẹja nínú pápá àti pé kí ọmọ yìí gbin iṣu ni ọjọ́ kan kí ó sì ta ní ọjọ́ náà. Ẹ ò rí pé àwọn iṣẹ́ yìí ṣòro púpọ̀ fún èniyàn láti ṣe. Ṣùgbọ́n rírò ni tèniyàn ṣíṣe ni t'Ọlọ́run. Bí orogún búburú yìí ti ń fún ọmọkùnrin ní iṣẹ́ yìí ni ìyá ń wò l'óde ọ̀run. Ìyá ọmọkùnrin yìí di ẹyẹ ó sì wá bá ọmọ rẹ̀, ó fii lọ́kàn balẹ̀ pé gbogbo iṣẹ náà ni ọmọ yìí yóò ṣe ni àṣeyọrí.

Bí ọmọ yìí ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀ ebè kíkọ ni ìyá rẹ̀ kó àwọn ogun ọ̀run dé tí wọn sì bẹ̀rẹ̀ sí kọ ebè náà.

Ọmọ náà bá fi orin bọnu báyìí pé:

Lílé: Onídere o, Ìdere ọ̀mọ̀
Ègbè: Ìgbà ǹ bá ti dé Ìdere ọ̀mọ̀
Lílé: Oní ń kọbe to kọrun
Ìdere ọ̀mọ̀

Ègbè: Ìgbà ǹ bá ti dé Ìdere ọ̀mọ̀
Lílé: Óní n pẹja nínú pápá
Ìdere ọ̀mọ̀ o

Ègbè: Ìgbà ǹ bá ti dé Ìdere ọ̀mọ̀

Lílé: Óní ń gbinṣu kọta lóọ̀jọ́
kan Ìdere ọ̀mọ̀

Ègbè: Ìgbà ǹ bá ti dé Ìdere ọ̀mọ̀

Bí ọmọ yìí ti ń kọrin ni àwọn ogun ọ̀rún bẹ̀rẹ̀ sí bá iṣẹ́ lọ títí ebè fig a tí ó sì kan ọ̀run. Bí wọ́n ti ṣe iṣẹ́ yìí tán ni ọmọkùnrin yìí lọ pe orogún búburú yìí kí ó wá wo iṣẹ́ náà. Ìyàlẹ́nu ni ó jẹ́ fún orogún búburú yìí láti ri wí pé lóòótọ́ ni ọmọ yìí ti parí ọ̀kan nínú iṣẹ́ tí òun ní kó ṣe. Obìnrin yìí kò dẹ̀hìn lẹ́hìn ọmọ yìí ó sì tún sọ fún kí ó lọ ṣe iṣẹ́ kejì, èyíùn ni kí ó pa ẹja nínú pápá. Ìyá ọmọdékùnrin yìí tún kó àwọn ogun ọ̀run wá tí wọ́n sì pa ẹja nínú pápá fún ọmọ yìí. Ẹ̀rù bẹ̀rẹ̀ sí ba orogún yìí, ṣùgbọ́n kàkà kí ó fi ọmọdé yìí sílẹ̀, ó ní dandan ó gbọ́dọ̀ ṣe iṣẹ́ kẹta. Ṣe ẹ̀yin náà mọ̀ pé aláṣejù wẹ́rẹ́ níítẹ́ bẹ́ẹ̀ni ti obìnrin yìí rí, kí ọmọ yìí tó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ kẹta èyí tí ó ní kí o gbin iṣu ní òòjọ́ kí ó sì ta ní ọjọ́ náà, ọmọdékùnrin yìí tún ti orin bọnu bí èyí tí ó kọ ní ìsáájú.

Bí ó tí ń kọ orin yìí ni àwọn ogun ọ̀run mú abàmì iṣu kan wá láti òde ọ̀run. Wọ́n gbin iṣu yìí, iṣu náà sì hù ní sànán kan náà, ó sì ta iṣu bọ̀kùà ní ọjọ́ náà, ẹnu ya orogún búburú yìí tó bẹ̀ẹ̀ gẹ́ẹ́ tí ó fi ń kábámọ̀ ohun tí ó ṣe. Ṣùgbọ́n ẹlẹ́ṣẹ̀ kì yóò lọ láìjìyà. Bí àwọn ogun ọ̀rin ti parí iṣẹ́ tan ni wọ́n sú mọ́ obìnrin yìí, ibẹ̀ náà ni ó ti ṣubú lulẹ̀ tí ó sì kú. Ṣé ẹ rí ẹ̀yìn òsìkà, òsìkà bálẹ̀ kú, ẹni tó dalẹ̀ kú, ẹni tó dalẹ̀ á bá ilẹ̀ lọ, ìtàn yìí kọ́ wa wí pé kí á mọ́ máa ṣe ìlàra ẹnikẹ́ni.

**Ìjàpá Àti Bùjé**

Ní ìlú kan ní ayé àtijọ́, ọmọbìnrin kan wà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Kerebùjé ṣùgbọ́n gbogbo ènìyàn gé orúkọ rẹ̀ kúrú sí Bùjé. Ọmọbìnrin yìí l'ẹ́wà púpọ̀, ó pọ́n fòò, gbogbo ara rí lómúlómú, ó sì ń dán bí jígí. Kín ni kan wà bá àjàó jẹ́, apá rẹ̀ gùn ju itan lọ, ọmọbìnrin yìí ní ìgbéraga púpọ̀ débi pé ó n fọ́nnu pé kò sí ọkùnrin kankan ní ìlú àwọn tí ó lè rí ìhòòhò òun, ní ìgbà tí Ìjàpátìrókò ọkọ Yánníbo, ọlọ́gbọ́n ẹ̀wé gbọ́ ọ̀rọ̀ tí Bùjé sọ yìí, ó sì pinnu láti ja ọ̀rọ̀ rẹ̀ àti pé òun yóò dójú ti Bùjé tí ìgbéraga rẹ̀ yóò lọ sílẹ̀. Ìjàpá sọ́ Bùjé dáadáa ó sì mọ ojú ọ̀nà tí ó máa ń rìn nígbà gbogbo, Ìjàpá yára lọ dá oko kan sí ẹ̀gbẹ ojú ọ̀nà náà. Ní ọjọ́ kan, Bùjé ń kọjá lọ, Ìjàpá yára gbé òkú ejò, ó náà dábùú ojú ọ̀nà tí

Bùjé yóò gbà. Bí Bùjé ṣe ń lọ ni ó rí ejò tí Ìjàpá nà sí ojú ọ̀nà. Ó rò pé ààyè ejò ni lái mọ̀ pé òkúejò ni. Bí Bùjé ti dé ibi tí ejò yìí wà, ni ẹ̀rù bàá, ó sì bẹ̀rẹ̀ sì pe Ìjàpá kí ó wá ran òun lọ́wọ́ láti pa ejò náà. ìjàpá gbọ́ igbe Bùjé, ó sáré wá sí ojú ọ̀nà, ó ṣe bí ẹni pé òun fẹ́ pa ejò, Ìjàpá da ẹ̀jẹ̀ tí ó tí bé sínú igbá kan sí ẹsẹ̀ rẹ̀ ó sì ṣe bí ẹni pé òun ti gé ara òun ládàá. Ìjàpá fi igbe bọnu, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí kọrin báyìí pé:

Lílé: Bùjé-Bùjé pa mi o
Ègbè: Kerebùjé
Lílé: Okoò mi mò ń ro
Ègbè: Kerebùjé
Lílé: Ọ̀nàà mi mò ń yẹ̀
Ègbè: Kerebùjé
Lílé: Ó ní n wá yà p'ejò
Ègbè: Kerebùjé
Lílé: Ò p'ejò p'ojúgun
Ègbè: Kerebùjé
Lílé: À pọ̀nọ́n nu ni n ó pọ̀n
Ègbè: Kerebùjé
Lílé: Àpọ̀n ẹ́yìn fasọya
Ègbè: Kerebùjé
Lílé: Ọ̀ bá gbé mi sí'bàdí rẹ
Ègbè: Kerebùjé
Lílé: Ìbààdí l'ayé wà
Ègbè: Kerebùjé
Lílé: Ìbààdí layé wà
Ègbè: Kerebùjé

Bí Ìjàpá ṣe ń kọrin yìí ni ó bẹ̀rẹ̀ sí ké ìrora tí ó sì ń sọkún. Gbogbo ènìyàn ti pé lé wọn lóri bí bàbèsùá, nígbà tí gbogbo ènìyàn rí bí Ìjàpá ṣe ń jẹ ìrora àánú ṣe wọ́n, wọ́n sì sọ fún Bùjé kí ó ṣe bí Ìjàpá ṣe wí. Nígbà tí àrọwà pọ̀, Bùjé fi ìtìjú gbé Ìjàpá sí inú rẹ̀, ó sì fi aṣọ bò ó mọ́ra, bí wọ́n ti lọ díẹ̀ ni Ìjàpá sọ fún Bùjé kí ó sọ òun kalẹ̀, ó wá sọ fún Bùjé pé òun ti rí ìhòòhò rẹ̀ kí ó ye ṣe ìgbéraga. Ojú ti Bùjé ní ọjọ́ náà, èyí ló sì fi òpin sí ìgbéraga Bùjé ní ìlú, ohun ìtàn yìí kọ́ wá ní pé kí á má máa ṣe ìgbéraga torí pé ìgbéraga ní síwájú ìparun, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe rí fún Bùjé.

Awọn Orogún Méjì

Ní ayé àtijọ́, ọkùnrin kan wà tí ó ní ìyàwó méjì. Àwọn ìyàwó méjéèjì máa ń sábà jowú ara wọn. Ìfẹ́ ojú lásán ni ó wà láàrin wọn. Nígbà tí ó di ọjọ́ kan, èyí ìyàwó yá ìgbákọ lọ́wọ́ ìyáálé rẹ̀ láti fi kọ ọkà nínú apẹ. Nígbà tí ó lo ìgbakọ yìí tán kò mọ ibi tí ó fi ọwọ́ rẹ̀ lé mọ́, Ó wáa títí kò ri. Ìyàwó kejì tí ó jẹ́ ìyáálé fi ààké kọ́rí pé òun gbọdọ̀ gba ìgbakọ òun, àṣé ìyáálé yìí náà ló d'ọ́gbọ́n mú ìgbákọ tí ó sì sọ sí inú odò, nígbà tí ìyáálé ń lọ sọ ìgbákọ sí odò, àwọn ènìyàn kan ríi tí òun kò sì rí wọn. Àwọn ènìyàn yìí náà lo wá sọ fún ìyàwó pé ìyáálé ti sọ ìgbákọ sí inú odò, bí ìyàwó ti gbọ́ èyí pẹ̀lú wàhálà tí ìyáálé gbé kò ó, ó múra, ó gba odò lọ, nígbà tí ó dé odò, ó rí ìgbákọ tí ó lé téńté lórí omi, ṣùgbọ́n nígbà tí o wo gbogbo wàhálà tí yóò bá òun bí òun kò bá mú ìgbákọ wálé, ni ó bá bẹ́ lu odò tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí kọrin báyìí pé:

Lílé: Ìgbakọ orogún mi dà
Ègbè: Teere nànà máa b'ódò lọ
Lílé: Ìgbakọ orogún mi dà
Ègbè: Teere nànà máa b'ódò lọ ǹsó

Báyìí ni ó bẹ̀rẹ̀ sí kọ orin tí ó ń lé ìgbákọ títí ó fi dé ọ̀dọ̀ Olúwẹri, nígbà tí ó dé ọ̀dọ̀

Olúwẹri èyí tíí ṣe Olúodò, ó bíi léèrè òun tí ó ń wá, ìyàwó ṣe gbogbo àlàyé bí iṣu ṣe kú bí ọ̀bẹ se bẹ́ẹ̀. Olúwẹri wòye ọ̀ràn ó sì rí wí pé ìyálálé obìnrin náà fẹ́ fìyà jẹ́ lásán ni, Olúwẹri wọlé ó kó dúkìá oníyebíye fún obìnrin yìí. Lẹ́yìn náà ni ó wá fún un ní ìgbakọ tí ó gbé e dé ọ̀dọ̀ rẹ̀.

Inú obìnrin yìí dùn, ó sì padà sílé, nígbà tí ó dé ilé ó pín dúkìà tí Olúwẹri fún un sí méjì, ó kó ìdá kan fún ìyáálé rẹ̀, ṣùgbọ́n eléyìí kò dùn mọ́ ìyáálé rẹ̀ nínú, ó ní òun náà yóò lọ sí ọ̀dọ̀ Olúwẹri láti gba dúkìá ti òun náà. Obìnbrin yìí mú ìgbákọ, ó kọrí sí odò, nígbà tí ó dé odò, ó sọ ìgbákọ sínú odò bẹ́ẹ̀ ni, ó bẹ́ sínú omi tẹ̀lé ìgbákọ náà. Bí omi ti ń gbé ìgbákọ lọ ni òun náà ń wẹ̀ tẹ̀lée. Nígbà tí ó dé inú ibú, Olúwẹri yọ síi. Olúwẹri bíi léèrè ohun tí ó fẹ́ tí ó fi wá sí ibú omi. Ó sọ fún Olúwẹri pé òun náà wá gba dúkìà tí òun bí ìyàwó òun ti ṣe. Olúwẹri bá fún ni àdó kan pé bí ó bá ti délé kí ó ti ìlẹ̀kùn mọ́rí, kí ó wá fọ́ àdó náà mọ́lẹ̀, Olúwẹri ṣe eléyìí láti fi ìyà jẹ alàìní ìtẹ́lọ́rùn obìnrin. Bí ó ti dé ilé ni ó wọ inú ìyàrá rẹ̀ lọ. Ó ti ìlẹ̀kùn mọ́rí, lẹ́yìn náà ni ó fọ́ àdó náà mọ́lẹ̀. Kín ni ó rí? Oríṣìíríṣìí ejò ló yọ sí tí wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí bùú jẹ títí ó fi kú, báyìí ni aĺàìnítẹ̀lọ́rùn obìnrin ṣe fi ọwọ́ ara rẹ̀ ṣe ara rẹ̀.

**Ọmọdé Kan Àti Ìyá Rẹ̀**

Ní ìlú kan ní ayé àtijọ́, ìyá kan àti ọmọ rẹ̀ wà, ìyá yìí fẹ́ràn ọmọ rẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni ọmọ náà fẹ́ràn ìyá rẹ̀. Nígbà tí ó di ọjọ́ kan àwọn ìpẹ́ẹ̀rẹ̀ ìlú, èyíùn àwọn ọ̀dọ́mọdé ìlú lọ sọ fún Ọba pé àwọn àgbàlagbà ìlú pàápàá àwọn obìnrin ń dá àwọn láàmú, wọ́n wá sọ fún Ọba kí ó jẹ́ kí oníkálùkù pa ìyá rẹ̀. Ọmọdé tí à ń sọ ọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí gbọ́, oí sì dá ọgbọ́n kan torí pé ó rò nínú ara rẹ̀ pé kò dára kí òun pa ìyá òun, ọmọ yìí wá gbé ìyá rẹ̀ pamọ́, kò sì jẹ́ kí ẹnìkan ó mọ ibi tí òun gbé pamọ́ sí. Nígbà tí Ọba rí pé gbogbo àwọn ọ̀dọ́ ti pa ìyá wọn tán pátápátá ni ó bá fún àwọn èwe ìlú ní ìdánwò kan ṣe. Ìdánwò náà ni wí pé kí wọn ó fi erùpẹ̀ hun okùn agba tí ó yi fún òun. Àwọn ọ̀dọ́ ìlú ro iṣẹ́ tí Ọba gbé fún wọn yìí títí wọn kò ja. Gbogbo wọn gbìyànjú láti ṣe iṣẹ́ náà ṣùgbọ́nkò ṣe é ṣe, ìbànújẹ́ dorí àgbà kodò fún àwọn ọ̀dọ́mọdé ìlú náà, níbi tí wọ́n ti ń ronú báyìí ni ọmọdeŕkùnriun tí kò pa ìyá rẹ̀ bá ronú ìyá rẹ̀, ó pinnu láti fi ọ̀rọ̀ náà tó ìyá rẹ̀ létí. Ọmọ náà bẹ̀rẹ̀ sí kọ orin báyìí pé:

Lílé: Ìyá-ìyá taakun wálẹ̀ o
Ègbè: Àlùjanjankíjan
Lílé: Ìyá-ìyá taakùn wálẹ̀ o
Ègbè: Àlùjanjankíjan
Lílé: Gbogbo ayé pa yèyé rẹ̀ jẹ
Ègbè: Àlùjanjankíjan

Lílé: Lágbájá pa yèyé rẹ̀ jẹ
Ègbè: Àlùjanjankíjan
Lílé: Tàmẹ̀dù pa yèyé rẹ̀ jẹ
Ègbè: Àlùjanjankíjan
Lílé: Mo gbé tèmi ó dọ̀run
Ègbè: Àlùjanjankíjan
Lílé: Ìyá-ìyá taakùn wálẹ̀ o
Ègbè: Àlùjanjankíjan

Bí ọmọ yìí ti ń kọ orin yìí ni ìyá rẹ̀ gbọ́ tí ó sì rọ wá bá ọmọ rẹ̀. Ọmọ rẹ̀ ko, ó rò fún un, Ó sọ bí iṣu ṣe kú àti bí ọ̀bẹ ṣe bẹ́ẹ̀ fún ìyá rẹ̀. Ìyá ọmọ yìí wá sọ fún ọmọ rẹ̀ pé kí ó sọ fún àwọn ọ̀dọ́mọdé kí wọn ó lọ bá Ọba, kí wọn ó sọ fún un pé àwọn ṣetán láti ṣe iṣẹ́ tí ó fún àwọn ṣùgbọ́n kí ó fi irú rẹ̀ tí wọ́n ti ṣe rí hàn àwọn nítorí pé ọmọ kì í bá ìpèlé ìyá rẹ̀ nílẹ̀ kí ó sì aṣọ dá. Inú ọmọ yìí dùn fún ìmọ̀ràn tí ìyá rẹ̀ fún un, Ó gbéra ó lọ sọ fún àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀. Àwọn ọ̀dọ́ lọ sí ọ̀dọ̀ Ọba, wọ́n sì sọ fún un bí wọ́n ṣe ran wọ́n sí i. Ẹnu ya ọba púpọ̀ fún ohun tí àwọn ọ̀dọ́ ṣe yìí ó sì rò nínú ọkàn rẹ̀ pé àgbàlagbà kan gbọ́dọ̀ wà ní ibìkan tí ó kọ́ àwọn ọ̀dọ́ ni ọgbọ́n yìí.

Ọba ṣe ìwádìí, lẹ́yìn rè ni ó wá rí wí pé ọmọdé kan kò pa ìyá rẹ̀, àti pé ìyá ọmọdé yìí ni ó kọ́ ọmọ rẹ̀ ni ọgbọ́n yìí. Ìtàn yìí kó wa wí pé kí á máa fi ojú di àwọn àgbà torí pé bí ọmọdé bá ní orin, àgbà á nítàn. Bí ọmọdé bá láṣọ bí àgbà kò lè ní àkísà bí àgbà.

Ọmọdékùnrin Àti Orogún Ìyá Rẹ̀

Ní ayé àtijọ́, àwọn obìnrin méjì kan wa. Ọkọ kan ló fẹ́ àwọn obìnrin méjéèjì. Ní ọjọ́ kan ọ̀kan nínú àwọn obìnrin yìí gba ọ̀nà ìrìnàjò lọ sí ìlú kan tí à ń pè ní Òjèéje. Nígbà tí obìnrin yìí yóò fi lọ, ó fi ẹyin sílẹ̀ fún ọmọ rẹ̀ láti máa jẹ, Ó fi ọmọ rẹ̀ ti orogún rẹ̀ kí ó máa bá òun mójú tó ọmọ òun, ṣùgbọ́n bí obìnrin yìí ti lọ sí ìrinàjò rẹ̀ ni orogún yìí pinnu láti fi ìyà jẹ ọmọ tí wọ́n fi só ọ. Ohun tí ó ṣe ni pé gbogbo ẹyin tí ìyá ọmọdékùnrin yìí fi sílẹ̀ ni orogún yìí bẹ̀rẹ̀ sí ṣe jẹ, tí ó sì ń fún ọmọ ní iṣu ewùrà tí ó ti kan gógó.

Nígbà tí ebi fẹ́rẹ̀ fọ́ ọmọdeŕkùnrin yìí lójú ni ó bá bọ́ sí ìtà ni ó bá ń kọ orin láti rán àwọn ènìyàn sí ìyá rẹ̀ àti láti fi ẹ̀hónú hàn sí ohun tí orogún ìyá rẹ̀ ṣe sí i. Bí ó ti bọ́ sí ìta ni ó bá bẹ̀rẹ̀ sí kọ orin báyìí pé:

Lílé: Èrò tí ń r'Òjéèje
Ègbè: Òjéèje
Lílé: Ẹ bá mi kí ìyá mi
Ègbè: Òjéèje
Lílé: Ẹyin tó fi sílẹ̀
Ègbè: Òjéèje
Lílé: Lorogún máa mú jẹ
Ègbè: Òjéèje
Lílé: Ewúrà tó kan gógó
Ègbè: Òjéèje
Lílé: Lorogún màà fún mi jẹ
Ègbè: Òjéèje
Lílé: Èrò tí ń r'Òjéèje

Bí ọmọdékùnrin yìí ti ń kọrin bẹ́ẹ̀ ni ó bẹ̀rẹ̀ sí wọlẹ̀, bí ìyá ọmọ yìí ti gbọ́ iṣẹ́ tí ọmọ rẹ̀ rán sí ni ó bá múra tí ó ń bọ̀ wá sí ilé. Kí ó tó dé ilé ọmọ rẹ̀ ti wọlẹ̀ dé ọrùn, ìyá yìí sáré sí ọmọ rẹ̀ láti fà á yọ ṣùgbọ́n ẹ̀pa kò b'óró mọ́, bí ìyá rẹ̀ ti ń fa ni irun ọmọ ń já mọ́ ọ lọ́wọ́ títí ọmọ fi wọlẹ̀ tán pátápátá. Ìtàn yìí kọ́ wa pé ìwà ìkà kò sunwọ̀n kí á ṣe rere.

Ọmọbìnrin Aláìgbọ́ràn

Ni ayé àtijọ́ ọmọbìnrin kan wà ní ìlú kan. Ọmọbìnrin yìí l'ẹ́wà bí egbin. Gbogbo àwọn ọmọkùnrin ni ó fẹ́ fi s'aya ṣùgbọ́n kò gbà fún ẹnìkankan nimnú wọn. Àwọn òbí rẹ̀ yan ọkọ fún un ṣùgbọ́n kò gbọ́ sí àwọn òbí rẹ̀ lẹ́nu.

Nígbà tí ó ṣe, ó bá ọmọkùnrin kan pàdé, ọmọkùnrin yìí r'ẹwà, ó sì wu ọmọbìnrin yìí dáadáa. Ó sọ fún ọmọkùnrin yìí pé òun nífẹ̀ẹ́ rẹ̀, òun sì fẹ́ kí ó jẹ́ ọkọ òun. Ọmọkùnrin yìí kọ̀ pé òun kò ní fẹ́ ọmọbìnrin yìí, ṣùgbọ́n ó fàáké kọ́rí pé ọmọkùnrin yìí ni òun ní láti fẹ́ láìmọ̀ pé sènìyàn-ṣeranko ni ọkùnrin náà, erè inú omi ni, ó paradà láti wá sí ìjọ àwọn adáríhunrun lásán ni. Nígbà tí ọmọbìnrin yií kò gbà, ni ọmọkùnrin yìí bá sọ pé òun yóò fẹ́ẹ, ó sì sọ fún ọmọbìnrin náà wí pé ilé òun jìnà. Ọmọbìnrin sọ fún un pé ibikíbi tí ọmọkùnrin yìí bá ń lọ òun yóò báa lọ.

Nígbà tí wọ́n rìn díẹ̀ tí wọ́n dé ibi tí àwọ̀ ọmọkùnrin yìí wà, ni ọmọkùnrin yìí bá yà sí inú igbó tí ó sì gbé àwọ̀ erè rẹ̀ wọ̀. Bí erè ti fà dé ojú ọ̀nà ni ó fa ẹsẹ̀ ọmọbìnrin yìí tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí gbé e mì. Bí ọmọbìnrin yìí ṣe rí ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ yìí ni ó bá f'ariwo ta pẹ̀lú orin lẹ́nu báyìí pé:

Lílé: Nìkún o, Nìkún ninì  
Ègbè: Nínínì, nìkún ninì  
Lílé: Nìkún o, Nìkún ninì  
Ègbè: Nínínì, nìkún ninì  
Lílé: Bàbá fimí f'ọ́kọ èmí ò gbọ́ o  
Ègbè: Nínínì, nìkún ninì  
Lílé: Ìyá fi mí f'ọ́kọ èmí ò gbà o  
Ègbè: Nínínì, nìkún ninì  
Lílé: Ọkọ nìkan tí mo fẹ́ lóbá derè o  
Ègbè: Nínínì, nìkún ninì  
Lílé: Nìkún o Nìkún ninì  
Ègbè: Nínínì, nìkún ninì

Bí ọmọbìnrin yìí ṣe ń kọ orin ni erè bẹ̀rẹ̀ sí gbéemì díè díẹ̀. Ṣé orí tí yóò sunwọ̀n nígb'áláwo rẹ ko ni, ọ̀kan nínú àwọn ọmọkùnrin tí wọ́n ti k'ọnu sí obìnrin yìí láti fi s'aya wà lórí ẹ̀gùn tí ó ń s'ọdẹ, bí ó ti gbé ojú wo ọ̀ọ́kán ni ó rí erè tí ó ń gbé ọmọbìnrin yìí mì. Bí ọkùnrin yìí ṣe ta ìbọn mọ́ erè nìyí tí erè sì kú. Lẹ́hìn èyí ni ọmọbìnrin náà yọ jáde lẹ́nu erè. Ìdí àlọ́ mi yìí ni pé kò yẹ kí á máa ṣe àìgbọràn sí àṣẹ àwọn òbí wa, kí á sì tún má máa ṣe fáàrí àṣejù, torí oko olówó ní í múni lọ.

Àfihàn Obìnrin Nínú Àṣàyàn Orin Àlọ́ Onítàn Yorùbá

Àwọn ohun tí ó jẹ wá lógún ní ìpele yìí ni láti ṣe àfihàn obìnrin nínú orin àlọ́ onítàn Yorùbá. A máa sọ̀rọ̀ nípa àpèjúwe ajẹmọ́ ìrísí, àfihàn rere obìnrin nínú orin àlọ́ onítàn Yorùbá bẹ́ẹ̀ ni a máa ṣe àfihàn búburú obìnrin nínú orin àlọ́ onítàn Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé obìnrin ṣe pàtàkì ní àwùjọ Yorùbá, obìnrin kì í ṣe àpínmógún, àtẹ̀mẹ́rẹ̀. Obìnrin ni iyọ̀ àti ìrèké ayé.

Àpèjúwe Ajẹmọ́ Ìrísí

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé onírúurú obìnrin ni Olódùmarè dà sí ilé-ayé, bí a ṣe rí arẹwà náà ni a rí òbùrẹwà gẹ́gẹ́ bí ìrísí obìnrin. Olódùmarè le ṣẹ̀dá obìnrin gẹ́gẹ́ bí arẹwà tí yóò sì ṣe ìtọ́jú ara rẹ̀ tí ẹwà rẹ̀ kò fi ní di ẹtì. Bákan náà, a rí òbùrẹwà obìnrin gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé Olódùmarè náà ló ṣẹ̀dá àwọn náà. Àwọn obìnrin mi wá tó jẹ́ pé àwọn ni wọn sọ ara wọn di òbùrẹwà gẹ́gẹ́ bí wọn kò ṣe mọ aájò ẹwà ara ṣe.

Obìnrin Gẹ́gẹ́ Bí Arẹwà

Èyí jẹ yọ púpọ̀ nínú àwọn àlọ́ onítàn tí a gbé yẹ̀ wò, nínú àlọ́ "Ìjàpá àti Bùjé", a rí i pé ọmọbìnrin náà rẹwà gán gẹ́gẹ́ bí wọn ti sọ nínú àlọ́ náà báyìí:

Ọmọbìnrin yìí l'ẹ́wà púpọ̀, ó pọ́n fòò, gbogbo ara
rí lómúlómú, ó sì ń dán bí jígí.

A tún rí ọ̀rọ̀ ẹwà obìnrin yìí bákan náà nínu "Ọmọbìnrin Aláìgbọ́ràn", nígbà tí apàlọ́ júwe ọmọbìnrin náà báyìí:

Ni ayé àtijọ́ ọmọbìnrin kan wà ní ìlú kan. Ọmọbìnrin yìí
l'ẹ́wà bí egbin. Gbogbo àwọn ọmọkùnrin ni ó fẹ́ fi s'aya

Àfihàn Rere

Obìnrin kì í ṣe ohun tí a lè ní kí Ọlọ́run yọ kúrò lọ́rọ̀ ọkùnrin torí pé "òbúkọ ní tòun di méjì lọ́dọ̀ ìyá òun, òhun ní ọmọ rẹ̀, bẹ́ẹ̀ òhun tún ni ọkọ rẹ̀.", bí ẹbí kan bá ń dùn yùngbàyùngbà tí gbogbo nǹkan sì ń lọ déédéé, ó wà lọ́wọ́ àwọn obìnrin ilé náà ni. Kódà bí baálé ilé kan bá ń gbé ohùn mèremère ṣe, tí ó sì ń jáde dáradára ó wà lọ́wọ́ aya tó gbé sílé ni.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé oríṣìíríṣìí obìnrin ló wà láwùjọ, bí a ṣe rí obìnrin rere náà ní a rí búburú, bí a ti rí obìnrin tí ó máa ń tí ọkọ lẹ́yìn náà ni a ní aya tí o máa ń gbé ọkọ lẹ́sẹ̀. Bí a ti rí nínú àlọ́ "Àwọn Orogún Méjì", Ìyàwó jẹ aya rere lọ́dọ̀ ọkọ, lẹ́yìn tí Olúwẹri fún un ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ dúkìá ó kó ìdá kan fún ìyáálé rẹ̀, kò tilẹ̀ ró nípa pé òun ní o jẹ́ kí òun bẹ́ sínú odò láti wá ìgbakọ rẹ̀ lọ, èyí fi hàn pé ìyàwó jẹ́ aya rere. Bákan náà, nínú àlọ́ "Ọmọdékùnrin àti orogún ìyá rẹ̀"orogún rere ni orogún tí ó fi ọmọ rẹ̀ sílẹ̀ fún orogún rẹ̀ láti máa mójútó ní ìgbà tí ó ń lọ sí ìrìnàjò, ìgbàgbọ́ rẹ̀ ni pé orogún òun yóò bá òun tọ́jú ọmọ náa bí i tirẹ̀, kò ní èrò búburú kankan lọ́kàn sí orogún rẹ̀ yìí rárá.

Obìnrin Gẹ́gẹ́ Bí Abiamọ

Kì í ṣe gbogbo obìnrin tó bímọ ni a lè pè ní abiamọ, obìnrin mìíràn kò ní ìtara ọmọ rárá, tó jẹ́ pé tí ó bá bímọ tán báyìí kò rójú ráyè ọmọ náà mọ́. Obìnrin mìíràn sì wá tó jìyà jìṣẹ́ lórí ọmọ rẹ̀ láti kékeré títí di àgbà, ṣe láti oyún níní ni àbí ìrìnàjò oṣù mẹ́sàn-án pẹ̀lú ọ̀pọ̀ ewu, àgàgà lọ́jọ́ ìkúnlẹ̀, ìyà àbiamọ pọ̀ lórí ọmọ. Nínú àlọ́ "Ẹyẹ àgbìgbò àti obìnrinn méjì", Ìfẹ́ tí obìnrin akúṣẹ̀ẹ́ yìí ní sí ọmọ rẹ̀ ló jẹ́ kí ó kọ̀ jálẹ̀ pé ọmọ òun ni kí àgbìgbò gbé padà fún òun tí ó sì kọ̀ jálẹ̀ pé òun kò fẹ́ dúkìá tí ẹyẹ àgbìgbò ṣèlérí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó wà nínú ìpọ́njú àti òsì, abiamọ tòótọ́ ni obìnrin yìí bí apàlọ́ ṣe ṣafihàn rẹ̀. Nínú àlọ́ "Ọmọdé Kan àti Ìyá Rẹ̀" abiamọ pàtàkì tí ìyá ọmọdé yìí jẹ́ ní ó mú kí ọmọdé yìí pinnu láti gbé iyá rẹ̀ pamọ́ nígbà ti àwọn yòóku ń pa ìyá wọn. Iyá ọmọdé yìí fi ara rẹ̀ hàn bí abiamọ rere nígbà tí ó fún àwọn ọmọdé ní ìmọ̀ràn rere nígbà tí wọn kò mọ ọ̀nà àbáyọ kúrò nínú iṣẹ́ tí ọba fún wọn láti se.

**Obìnrin Gẹ́gẹ́ Bí Oníwàrere**

Àwọn obìnrin kan wà tó jẹ́ pé oníwàrere ni wọ́n, àwọn obìnrin mìíràn sì wà tó jẹ́ pé ìwà ọwọ́ wọn kù díẹ̀ káàtó. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí nínú àlọ́ "Ẹyẹ Àgbìgbò àti Obìnrin Méjì". Lẹ́yìn tí ẹyẹ àgbìgbò ti fún obìnrin akúṣẹ̀ẹ́ ní dúkìá àti ọrọ̀ iyebíye, obìnrin akúṣẹ̀ẹ́ yìí gẹ́gẹ́ bí oníwàrere pín dúkìá náà pẹ̀lú iyàálé rẹ̀ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyáálé náà kọ̀ ọ́. Bákan náà, nínú àlọ́ "Àwọn Orogún Méjì" ní ìgbà tí olúwẹ̀rí rí i pé oníwà rere ní ìyàwó àti pé ṣe ni ìyálé rẹ̀ fẹ́ fi ìyà jẹ ẹ́ lásán, ó kó dúkìá olówó iyebíye fún un. Iyàwó yìí kò fi ti ìwà burúkú tí ìyáálé rẹ̀ hù nípa ti ìgbakọ rẹ̀ se, o fún orogún rẹ̀ yìí lára dúkìá náà, sebí Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ìwà kìí fi oníwà sílẹ̀.

**Obìnrin Gẹ́gẹ́ Bí Òjòwú**

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé ní àwùjọ kò sí obìnrin tí kì í jowú ṣùgbọ́n bí a ṣe le jowú sì ló yàtọ̀ sí ara wọn. Gẹ́gẹ́ bí a ti rí nínú àwọn àlọ́ wọ̀nyìí. Nínú àlọ́ "Ẹyẹ Àgbìgbò àti Obìnrin Méjì", owú tí obìnrin olówó ní ni ó mú kí ó gbé ọmọ rẹ̀ lọ sí inú igbó tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí ní bẹ ẹyẹ àgbìgbò pé kí ó wá gbéọmọ òun. Gẹ́gẹ́ bí apàlọ́ ṣe sọ ẹyẹ yìí mọ̀ pé òjòwú ní obìnrin ọlọ́rọ̀

yìí, ó sì pinnu láti kọ́ọ lọ́gbọ́n. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú àlọ́ yìí: Owú àbaadì ló sọ obìnrin òjòwú yìí di alaìlọ́mọ láyé, sé Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ìtẹ́lọ́rùn ni baba ìwà.

A tún rí èyí náà nínú àlọ́ "Orogún Búburú", ìyáálé jowú ìyàwó rẹ̀ torí kò bí ọmọkùnrin, lẹ́yìn ìgbà tí ọkọ rẹ̀ àti ìyàwó rẹ̀ yìí tí ó bí ọmọ tún kú tàn, owú yìí kan náà ní kò jẹ́ kí o fí ọmọkùnrin yìí lọ́rùn sílẹ̀ títí tí àwọn ogun ọ̀run fi ṣe ìdájọ́ òjòwúbìnrin.

Obìnrin Gẹ́gẹ́ Bí Ọ̀dájú Ènìyàn

A lè rí èyí nínú àlọ́ "Ọmọdékùnrin àti orogún ìyá rẹ̀" Ìwà ọ̀dájú ni orogún ìyá ọmọdékùnrin yìí hù tó rí i pé nígbà tí obìnrin yìí yóò fi lọ, ó fi ẹyin sílẹ̀ fún ọmọ rẹ̀ láti máa jẹ, Ó fi ọmọ rẹ̀ ti orogún rẹ̀ kí ó máa bá òun mọ́jú tó o, ṣùgbọ́n bí obìnrin yìí ti lọ sí ìrinàjò rẹ̀ ni orogún yìí pinnu láti fi ìyà jẹ ọmọ tí wọ́n fi só ọ. Ohun tí ó ṣe ni pé gbogbo ẹyin tí ìyá ọmọdékùnrin yìí fi sílẹ̀ ni orogún yìí bẹ̀rẹ̀ sí ṣe jẹ, tí ó sì ń fún ọmọ ní iṣu ewùrà tí ó ti kan gógó. Ọ̀dájú ènìyàn pọ́ńbélé ni orogún yìí jẹ́.

Obìnrin Gẹ́gẹ́ Bí Ìkà/Ẹni Ibi

Gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú àwọn àlọ́ "Àwọn obìnrin méjì" ìyàwó yá ìgbákọ lọ́wọ́ ìyáálé rẹ̀ láti fi kọ ọkà nínú apẹ. Nígbà tí ó lo ìgbakọ yìí tán kò mọ ibi tí ó fi ọwọ́ rẹ̀ lé mọ́, Ó wáa títí kò ri. Ìyàwó kejì tí ó jẹ́ ìyáálé fi àáké kọ́rí pé òun gbọdọ̀ gba ìgbakọ òun, bẹ́ẹ̀ ìyáálé yìí kan náà ló d'ọ́gbọ́n mú ìgbákọ tí ó sì sọ sí inú odò, nígbà tí ìyáálé ń lọ sọ ìgbákọ sí odò, àwọn ènìyàn kan rí i tí òun kò sì rí wọn. Àwọn ènìyàn yìí náà lo wá sọ fún ìyàwó pé ìyáálé ti sọ ìgbákọ sí inú odò, bí ìyàwó ti gbọ́ èyí pẹ̀lú wàhálà tí ìyáálé gbé kò ó, ó múra, ó gba odò lọ, nígbà tí ó dé odò, ó rí ìgbákọ tí ó lé téńté lórí omi, ṣùgbọ́n nígbà tí o wo gbogbo wàhálà tí yóò bá òun bí òun kò bá mú ìgbákọ wálé, ni ó bá bẹ́ lu odò. Ìká àti ẹni ibi ni ìyáálé yìí jẹ́, amọniseni sì ni pẹ̀lú.

**Àgbálọgbábò**

Àlọ́ tí ó jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí àwọn Yorùbá máa ń gbà láti kọ́ ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ èyí tí ó ń fi ọgbọ́n, ìmọ̀, òye, ìgbàgbọ́ àti ìṣesí àwọn Yorùbá hàn ní a ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ nínú iṣẹ́ àkanṣe yìí. A sọ̀rọ̀ nípa ọ̀nà tí a gbà ṣe àfihàn obìnrin nínú orin àlọ́ onítàn Yorùbá, gẹ́gẹ́ bí o ṣe jẹyọ, ọ̀nà méjì gbòòrò ni a gbà fi obìnrin hàn nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá. Lọ́nà kíní a fi obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí aya rere, abiamọ tòótọ́, àti oníwà rere, bákan náà ni a tún fi obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí òjòwú, ọ̀dájú àti ìkà. Ìgúnlẹ̀ iṣẹ́

ìwádìí yìí ni pé lòdì sí ohun tí àwùjọ ń sọ nípa obìnrin kìí ṣe pátápátá ni ọ̀pọ̀lọ́ obìnrin kò nírù, bẹ́ẹ̀ ni kìí ṣe pé kò sí iṣẹ́ rere kankan lọ́wọ́ àwọn obìnrin. Fún ìdí èyí, ojú àìsègbè tí a fi wo obinrin nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá ni ó yẹ kí àwùjọ ṣe àmúlò, kí wọ́n fi ahọ́n rere pe obìnrin ni ibi tí ó bá ti yẹ, kí ìtẹ̀síwájú àti ìdàgbàsókè lè wà láwùjọ.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


Acholonu, R. (1999). "*Women in the African Novel and the Quest for Human Rights"* in Beyond the Marginal Land, Opara, C. (ed.) PortHarcourt: Belpot.

Adébáyọ̀, A. (ed.) (1996). "*Tearing the Veil of Invisibility: the Roles of West African Female Writers in Contemporary Times*" in Feminism and Black Women's Creative Writing. Ìbàdàn: AMD Books.

Akóredé, Y. O. (2011). *Feminism and Literature: Womanism and the Intra-Gender Conflict Theory*. Republic of Benin: National Library Publishing (ESAF).

Amọo (2010) *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Àpagbè.* Ọṣogbo: Mabol Trust publishers.

Babalọla (1974). "*Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá Apá Kìn-ín-ní"* University Press PLC.

Babatunde (1994) *Obìnrin Nínú Ìṣẹ̀lú Ilẹ̀ Yorùbá,* Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan.

Bádé Àjàyí (2015). *Ìtúpalẹ̀ Àlọ́-Àpamọ̀ Yorùbá.* Unilorin Press, University of Ilorin, Nigeria.

Bascom (1940). "Literary style in Yorùbá Riddles", *Journal of American Folklore*, Vol. 20, No. 1:1-32.

Bọ̀dé Agbájé (2013). *Àlọ́ Nínú Àṣàyàn Yorùbá*. Elyon publishers.

Culler Jonathan (1975). *Struturalist Poetics, Structuralism Linguistics and Literature*, New-York. Cornell University Press.

Fasehun, M.A. (2009). "*Àtúnyẹ̀wò ohun tí Ifá Sọ Nípa Obìnrin" nínú Láàńgbàsà* (Jọ́nà Iṣẹ́ Akadá Ní Èdè Yorùbá). University of Lagos. Lagos: JOYTAL.

Fasehun, M.A. àti Òjó, I. F. (2015). "*Obìnrin ni Ọ̀tá Ara Rẹ̀" nínú Baawà:* Jọ́nà Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá, Fọ́lúùmì 1, Nọ́ńbà 1, o.i. 89-95.

Ilésanmí, T.M. (2013). Obìnrin: *A Cultural Assessment of Yorùbá Woman.* Nigeria: Astra Multimedia Nig. Ltd.

Kọ́láwọlé, M.E.M. (1987). *Woman and African Consciousness*. Trenton, New Jersy: African World Press.

Ọbáfẹ́mi, Olu, (2008). "*Gender Politics and Theory in a Democratic Culture: The Nigerian Female Writers Perspectives."* nínú Olú Ọbáfẹ́mi, Public Discourse in Humanities. Ibadan: University Press Plc. o. i. 79-88.

Ògúndípẹ̀-Leslie, O. (1984). '*Not Spinning on the Axis of Maleness'* Morgan, R. (ed.) Global New York: Anchor Double Day.

Ojo, Ọlagoke (2005) *Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yánníbo*. Lagos:Learn Africa Plc.

Ọlabimtan, A. (1982). "*Form and Meaning in Yorùbá Riddles",* Nigeria Magazine No. 140:66-76.

Ọpadotun, O. (1994). *Àsàyàn Àlọ́ Onítàn.* Ibadan: Y-Book.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, A. (2009). *Women in Yorùbá Culture: A* Dozen of Academic Articles. Nigeria: Penthouse Publications (Nig.).

Yai, O. (1977). Some Structural Aspext of Yorùbá Alo-Àpamọ̀ (Riddles)", Seminar series part II. Oyelaran (ed.) 419-62.

Smith, (1985). "*Racism and Women's Studies"* Hull, G., Scot, P.B. & Smith, B. (eds.)

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** BỌ́LÁRÌNWÁ, Abídèmí. Àfihàn obìnrin nínú àwọn àsàyàn orin àlọ onítàn yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 202-215, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Bọ́lárìnwá, Abídèmí. (jan./jun.2025). Àfihàn obìnrin nínú àwọn àsàyàn orin àlọ onítàn yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 202-215.